# OLOLA GOMINA MACPHERSON TI PADA DE

# IROHIN YORUBA

Ẹda Oro Wa— "IWAJU L'OPA ẸBITI NRE SI"


**Akiyesi**

A fẹ ki awọn onibara wa ma san owo si apo wa dede, ẹniti ko ba san owo tirẹ, ki o ma ya a lẹsẹ bi a ba da a duro lojiji, a o si gba owo wa lọwọ rẹ.

OLOTU
IROHIN YORUBA


OBA LAWANI OLUPO AJASE IPO W'AJA; AWỌN OLOYE OLOGUN LO YO F'ALAKE

VOL. I[illegible] NO. 695 IBADAN, MONDAY DECEMBER 10 19[illegible] OWO IWE IROHIN YORUBA [illegible] 1d)




ỌGBẸNI ANTHONY EDEN
Aṣoju Ijọba Gẹẹsi fun awọn ilu ominira. (Foreign Secrary of the British Government.)



Ọgbẹni Winston Churchill
Oloye Baṣọrun Ilu Gẹẹsi
(Prime Minister of Great Britain)

Ẹniti o wa lori oye Baṣọrun yi ni asiko ogun ajakaiye Keji Ki Ọgbẹni Clement Attlee to wa gba ipo rẹ nigbati ogun pari. Lọdunni ni on na si tun wa gba ipo na pada lọwọ Ọgbẹni Attlee.



ỌGBẸNI OLIVER LYTTLETON
Aṣoju Ijọba Gẹẹsi fun awọn Ilu Amọna Gẹẹsi (Secretary of State for the Colonies).

## Gomina Pada De

Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi ni Ọlọla John Stuart Macpherson G.C.M.G. ti iṣe Gomina Nigeria pẹlu Iyawo rẹ bà ọkọ Ẹlẹfin "R. M. M. V. Apapa" de si Eko, Ẹniti o ti lọ si ilẹ rẹ fun isinmi, Aṣoju Ijọba, Ọgbẹni A. E. T. Benson ati awọn Ọga Pataki-Pataki ninu iṣẹ Ọba pẹlu awọn ọlọla ilu ni o lọ pade rẹ. O si ti bẹrẹ si ṣe iṣẹ-alakoso ilu Nigeria nisisiyi gẹgẹ bi o ti ti nṣe e tẹlẹtẹlẹ ri.

### YISA GBE ỌMỌ-ỌBA NI IYAWO

ILORIN—Ni ọjọ kejila oṣu kẹwa ọdun yi ni Ọgbẹni Yisa ọmọ Musa gbe Omidan Adedigba ọmọ Ọba Ilọrin ni iyawo, awọn Ọlọla ati gbajumọ pupọ wa si ibi igbeyawo na, inawo ọjọ na ka-ma-ma Ayanlọla ni elere ọjọ na.

Ayanlọla wa npe ọkọ iyawo Yisa ọmọ Musa ni oriṣiriṣi oriki, ka sọ otitọ Ọlọrun pọn Yisa le ni Ilọrin pupọ. Adisa ọmọ Salamọtu, Ọlọrun yio fi ọmọ rere ṣikẹ iyawo o.

Ọjọ na miringindin fun Ọgbẹni J. A. Arẹgbẹ ti iṣe ọrẹ oko iyawo. Diẹ ti ayo wa fun lati daruko ninu awọn ti o wa nibẹ ni Ọlọla Yaya, S. O. Okin, Tafa Wolewole, Akanni Ibadan, Adedokun Ogbomọṣọ ati ọpọlọpọ ẹnia.

A dupẹ lọdọ D. H. Balab-Alao ọgọ ọmọ Awawu, ẹṣeki!

### ỌGBẸNI DAVID LATUNDE DI BABA ẸGBẸ

ẸDẸ—Oriṣi inkan ayọ mẹta ni a ṣe ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu kẹwa ọdun yi ninu Ṣọọṣi Ijọ African Church Oke Ẹgan, Ni ọjọ na ni a fi Ọgbẹni David A. Latunde ile Olodoeba jẹ oye Baba Ẹgbẹ Ijọ African Church Oke Ẹgan, a ṣe isin idupẹ oṣọọṣu ati ajọyọ ajọdun adọta ọdun (Golden Jubilee) Aṣanyan orin pataki ni a lo fun isin ọjọ na, a si gbadun Ọgbẹni J. O. Latunde bi o ti nfi ika ṣe ṣere lori duru, a si gbadun awọn ọmọ ile iwe ti nwọn kọ orin na pẹlu ilu ti o nba a mu rẹgi.

Oniwasu ọjọ na ni Ọgbẹni Samuel Ọpẹṣina, iwe Joṣua ori kini ẹsẹ karun ati ikẹfa "Ṣe giri ki o si mu aiya le" ni o fi gba wa ni iyanju, Nigbati a pari isin, lati ibẹ ni awọn ọmọ ile iwe ti bẹrẹ si kọrin aladun titi a fi de ile Baba Ẹgbẹ.

Ọgbẹni Samuel Obaṣina pẹlu S. A. Adebiyi (S. M. Ẹdẹ) ni o ṣe adura ki a to bẹrẹ si jẹ ase ti Baba Ẹgbẹ ti peṣe silẹ. Onjẹ oriṣiriṣi, ọga, obi ati orṣiriṣi oti oyinbo ko ni onka, Ọgbẹni A. J. Latunde aburo Baba Ẹgbẹ ṣe inawo pupọ ni ọjọ na.

Diẹ ti ayo wa fun lati daruko ninu awọn ti o wa nibẹ ni Oloye Osi Balogun, S. A. Adebiyi (S. M. Ẹdẹ) S. P. Ọjẹdoyin, Samuel Ọpaṣina, Daniel Ọpaleke, Adewusi, Gabriel Adeṣọla ati ọpọlọpọ ẹnia ti ko si aye lati daruko wọn. Oye a mọri o Baba Ẹgbẹ.

## Ọba Ajase Ipo W'aja

Ni ọjọ Oj'bọ ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu ti o kọja yi ni Ọba Alaiyeluwa Lawani Arojo, Olupo Ajaṣẹ-ipo w'aja nigbati o di ẹni ọdun mọkan-dinlọgọrin l'aiye, nigbati o di ọdun mẹdogun lori oye.

Ni asiko ti o jọba Ilọsiwaju ati ọpọlọpọ idagbasoke wa fun gbogbo ilu abẹ ijọba rẹ, on paapa si jẹ ẹniti o fẹran ẹnia pupọ ben awọn ara ilu rẹ si fẹran rẹ pupọ nitoripe bi o ti wu ki ọran kan la to ni ilu rẹ ko jẹ ko lati fi aiya di i, Idi eyi ni o mu ki awọn Ọlọpa fi mu u ni ọjọ kọkanla oṣu kọkanla ọdun 1949, ni igbati o nja fun ilu rẹ lati kuro labẹ ijọba Hausa, On ni Olori Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa Ajaṣẹ-Ipo.

Ẹnia pọ pupọ nibi isinku rẹ. Iru ẹye isinku bẹ ẹ ti ṣẹlẹ ni Ajaṣẹ-Ipo ọna na jin nitoripe ọpọ ẹnia ni o wa lati Abẹokuta, Ibadan, Kano, ati ọpọlọpọ ilu miran. O fi ọpọlọpọ ọmọ ati ọmọ-ọmọ l'okunrin l'obirin silẹ ti ko si aiye fun lati daruko wọn. Ki Ọlọrun jẹki ẹhin Ọba na o dara o.

Ẹ maa ka iwe
**Irohin Yoruba**
alghagbogbo fun ọriṣiriṣi irohin

## Oloye Ologun Lo Yo F'Alake

Ni aipẹ yi ni awọn ijoye Ologun Ẹgba lọ yọ fun Ọba Alaiyeluwa Ademọla Keji Alake Abẹokuta fun alafia ti o wa ni ilu lati igbati Ọba Alake na ti pada bọ si ilu Abẹokuta.

Awọn ijoye Ologun ti o wa ki Ọba Alake na lọ ni igba, ẹniti o ṣe aṣiwaju awọn oloye na lọ si ọdọ Ọba ni Oloye J. B. Majekodunmi Otun Ẹgba, lẹhin ti nwọn ki Ọba Alake ku orire alafia ti o wa ni ilu Ẹgba tan, ni nwọn ba tun ṣe ileri pe awọn wa fun un lati ma a ba a gbamuran papo fun gbogbo eto ti o ba ti jẹ mọ ti ilu.

Inu Ọba Alake na si dun pupọ fun kiki ti awọn oloye wonyi wa ki i, o si dupẹ pupọ lọwọ wọn fun ileri ti nwọn ṣe lati wu ti ifọwọsowọpọ pẹlu on ati gbogbo awọn Oloye Ẹgbẹ yoku fun ilọsiwaju ilu Ẹgba. Nwọn si fi ọjọ na ṣe onje pẹlu Ọba Alake ni aafin rẹ. O si fi jijẹ ati mimu rẹ wọn lọrun iti nwọn fi pari ariya n .

OWE :— AGBALAGBA KI IWA NILE K'ORI ỌMỌ TITUN O FA

